Chief Secretary to the Govt

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI No 307 SATURDAY, DECEMBER 29 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

-4 JAN. 1929 LAGOS

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N.B.—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
SLOAN'S
N&B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Carton adopted 1916.
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Keep away
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

DẸDẸ O ẸYIN JANDUKU.

A gbọ pe o to iwọn adọjọ bilala tabi koboko ti awọn Ọpa ọba gba lọwọ awọn ti nwọn nwọde aisun ni *Monday* tokọja nigbati aisun *Xmas* wọle, o si ni iye awọn ti a sọpe awọn Ọlọpa mu fun iwa jagidijagan ni alẹ ọjọ kana.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

EWU ỌDUN ṢA NI KI A MA KI 'RA.

Nwọn ṣe ọdun Keresimesi ni ọjọ Atalata ijarun 25 *December*, a ko ṣai mọ gẹgẹbi ọdun na ti dun to, bẹni ki a ma wi, bo pẹ titi adun ni yio gbẹhin ewuro, adura ti wa ni pe ki Ọlọrun ṣa mu ayipada rere wa larin ọdun titun ti a o bọ si ni ọjọ mẹrin loni.

AṢEJU BABA AṢETẸ

O dun mọ wa ninu jọjọ nigbati a gbọ wipe nwọn ko gba ti awọn ọmọ ipata ti nwọn ma nyọ awọn enia lẹnu lọdọdun nipa lulu ara ẹni ni aye ni alẹ ọjọ aisun ọdun, to bẹ ti nwọn fi ni ngba pọpa kiri lọwọ ẹnikẹni ti nwọn ba tiri.

BASA! BASA!!

Awọn Ṣọṣi ijọ U.N.A., ti Ebute-Mẹta ta Basa ni Ṣọṣi wọn ni ọjọ Jimọ ana.

O TO AYỌ GAN!

A gbọ wipe awọn kan nla ijo mọra ni adugbo kan larin ọsẹ ti o kọja, pe awọn fi nyọ ayọ Ikoyi ti awọn ti bọ—ko ha to bẹ?

ỌYẸ-AMUKARA.

Ojo ti o rọ ni ọsan ọjọ Alaruba lo fa ọyẹ-amukara wọ ilu ti gbogbo enia fi ka 'wọka 'sẹ bọ inu bi ahun, nibẹ ẹwẹ awọn ẹlomiran ko tilẹ mọ pe alare nja agba.

OṢU AWỌN ALAPARỌ LE E.

Ko si ẹniti obinrin rere to dara loju to si ni ẹwa ko wun wipe kari ni ita, ko wọ aṣọ eyiti iya rẹ ko wọ ri, ko wọ bata oniyebiye eyiti awọn obi rẹ ko le fi rin, ko ma sọ apalapulu oyinbo eyiti awọn panṣaga ẹgbẹ rẹ, ma ro wipe oyinbo ara wa yi, ko si irufẹ rẹ, ko ma fi aṣọ wiwọ ijọ ọsẹ ko ma fi se onjẹ, ki awọn ẹgbe tabi ẹgbọn ati aburo ki wọn ma sọ wipe ẹgan ni hẹ, ti ara wa yi, ko wọ pọ, ninu dunia ni onjẹ sise tabi aṣọ wiwọ, ọlẹ ko mọ wipe ohun to pọ ntan, to ba si ri apa wipe obinrin yi ko si ẹniti o to fẹ ayafi emi nikan, iwọ amumimurawe anu ẹ nṣe wa wipe ori agbebọ adiẹ lọja o sare mọ, oye ogun opa ogun ni ẹlẹdiẹ gbe wa ja, o le ni oto ni ẹnu ko de ọdọ wọ, o le ma ṣe ododo nibi ti ogbe wa, ki iwọ wa ri gbe ti iwọ ra wipe iwọ ngbe nkan daindain, ọpọlọpọ wọn lo wa ni ilu loni, ti won nwọ ngboro kiri, omiran aya Boy Boy lo jẹ nitori ọga rẹ, ọpọlọpọ miran nkan nlanla lo nwu wọn nipa bẹ wọn a sọ ara wọn di enia lasan nipa iwa agbere, mo ni ran lọjọ kan nibi ere ẹṣin lọdan, ngbọ awọn panṣaga ti wọn nfẹ oyinbo ti wọn nfi orukọ oyinbo laju nipa agbere ni kọ ni awọn ọmọ onibi ntan ti wọn lo gbe nkan buruku wọn yi wa sibi ere ẹṣin,, to jẹ wipe ẹgbẹ ẹja ni ẹja nwẹ le, awọn panṣaga ẹgbẹ wọn to jẹ wipe ajo pade Lọya. Dokita, Messenger ati akowe ni wọn nṣẹju si iran awọn Baba ẹni wọn yi, wọn ni orukọ ni Eko ri, ọpọlọpo awọn miran ti ọrọ ẹbi ba sori korido si wọn, ti aluba aiye ba fi ọwọ ba wọn, ile awọn panṣaga yi ni wọn ma ko si, ti panṣaga yi, ba wa mu ale ati ọrẹ wọle ti iwọ ọkọ aramu, iwọ ti koroba rẹ ko kara mọ debi to ma to odo, to ba ni bawo ni, odi wipe ki iyawo ọsan gangan yi ma sọ fun ẹ wipe ile Baba rẹ niyi, ti iwọ papa ba wa fi idi mulẹ ajẹ wipe ọmọ ale haunhaun ni ọ, ọmọ ale miran wa to jẹ wipe Baba kan gba ṣa, nitori na bo ti wun ko ri iwa ọmọ ale lo ma hu, bi iwọ ki ba ṣe ọmọ ale, ile aya yi lo yẹ ki iwọ ma gbe bi iwọ ba ni ojuti, ile ti iwọ ko le na apa ko na ẹsẹ, Oluwa ko gba ni, ninu aṣiṣe aiye, Oluwa ko fi wa mọ ọna, omiran ẹwẹ to ba jaja ri ọkọ yẹn mu, nipa iṣẹ eṣu to nṣe yio ro wipe gbogbo nkan ni lati ma lọ bẹ, wipe ko si aiye nibi kan mọ, ṣugbọn gbogbo rẹ nkọ lo si ofo ijo keji oja, ngbọ iwọ ọkunrin to gbe panṣaga dani, to wa nsọ wipe ko si irufẹ aya rẹ, o bẹru rẹ pupọ, otọ lo ti nṣe panṣaga ṣugbọn o ti da gbogbo rẹ silẹ, owa fi ara balẹ fun ọ, aran lo nba ja, ẹda

lo nyọ lẹnu, gbogbo wọnyi le ṣe alai gbọn owo ọkọ tọhun danu ko wa ti si ta fun e, ki iwọ ma lo ran iyoku? Iwọ onitẹkufẹ ọkunrin ronu piwada, ko mọ on to ma fi ṣẹ ile rẹ? Abi iwọ ma gbe awọn Rabiatu onigba egbere sile fun awọn ọmọ ọjẹka ki wọn ma du mọ o lowo. Ọpọlọpọ ni awọn ti ọfa iwe yi ba ti wọn nja apoto wipe emi ki ṣe egbẹ awọn alaparọ iwọ onişekuşe tani ba ọ wi, bi iwọ ki ba ṣe alaparọ kini ọrọ yi ti ṣe le ba ọ wi, mi o ba o wi, ṣe ori rẹ gbe ọ ko Sugọmu kan amumi mu rawe, to ṣe bi nkan gunmo ni on gbe dani, ngbọ bo jẹ alaparo bi iwọ ki ṣe panṣaga ti iwọ ko si jẹ ẹniti okọ la loju aṣọ mo kan sara si ọ. ẹniti oyinbo ko ni aṣọ wọ, ẹniti oyinbo ko kọ mọ, iwa agbere jẹ iwa idojuti, iwa irẹni silẹ, ẹnikẹni to wun ko gbe panṣaga dani, ki ṣe epe, oluwa rẹ yio ma lọ silẹ ni, ọla rẹ yio ma buku, ko ni ni ibugbe iyẹn da mi loju, nitori pe gbese lo ma ki ọrun bọ, awọn ọkunrin miran nma tu ara wọn ninu wipe ofẹ yi pada, ẹniti to ma yi pada, lo ma di alupa moku lọsan loru ni ọwọ rẹ, ẹniti o ma yi pada ni ko ni fi ojo tirẹ gbin oka ninu ohun kohun to ba nṣe! Ngbọ ẹnyin alaparọ mọ ara yin, ko ni si ṣẹ ko ni si abọ, igboro ni wọn nwọ kiri, ngbọ tani ma bere lọwọ obinrin to fi gbogbo ọmọ bi obinrin wipe kini awọn ọkunrin ṣe nwọ lọdọ awọn ọmọ rẹ, nṣe ni wọn ngbajumo. Nitori na mo bẹ nyin ẹnyin alaparọ ki e ronu piwada ninu odun ti a ma mu ni ijọ mẹrin loni wipe ki Ọlọrun yi ọ pada si rere. Iyoku di ọwọ yin, mo sọ temi na temi na di ọwọ Soko.

## WỌN FUN Ẹ NILE, O NKUN LẸFUN O GBỌN TO ẸNI TO KỌ.

Ngbọ ọpọlọpọ lode Eko loni yi, ti Ọlọrun ba fi si aye re ni aiye yi yala ipo giga nibi iṣẹ ni. yala Ọlọrun ṣe asiki fun ni ọna owo ni, kaka ko fi owo ṣe nkan pataki, ile gbogbo ẹbi ni oma ma na owo le lori, ti awọn ọlogbọn yoku ma ma wo, ti wọn ma ına fi ọwọ lẹran, nigbati omugọ yi ba ro wipe nkan ki kan ninu ẹbi ki on ma dide si, yala ọna owo ni tabi ọna miran, nipa bayi yio ro wipe on ti di Mọgaji gbogbo ẹbi, ṣugbọn ẹnyin ara mi to ba di ẹhin ọla nkọ, awọn ọmọ baba rẹ yoku ati awọn ọmọ iya rẹ wọn ko ni gbe ogun dide si, wipe awọn nfẹ ipin ile awọn? Ọrọ to mu labari yi wa sori mi nipe mo niran ni aipẹ yi, ọrọ ile kan wa si Kotu nla ganran mo ri wipe niwaju Adajọ Webber ni, nipa ile kan nibi ọgba St. Anna, ile ti ọkan ninu ọmọ baba yi kọ Pẹtẹsi pọn gba pọn gba, to sọ wipe Baba on ti fun on, ko to di wipe on kọ pẹtẹsi si, ngbọ nigbati ẹbi rẹ dide si, ti wọn gbe ọrọ yi lọ si Kotu nla nkọ? Adajọ ko fi are fun awọn ẹbi wipe ile na ile ẹbi ni, nitori pe orukọ rẹ ko si ninu iwe ile yi, nipa bẹ ile aramu ni iwọ lọ! Iwọ omugo to ngbiyanju ati tun ile ẹbi ṣe, o fi eyi kọgbọn, wipe bo di ẹhin bo bere owo lọwọ ẹbi wipe ki wọn san owo titun ṣe fun o, wọn asi sọ wipe ko ṣiro igba ti oti nlo ile yi ni ọfẹ

la lai san wo, to nti ara rẹ han bi Mọgaji Sak (ile ti awọn Munisiba kọ si Yaba) to si ro wipe iwọ olori ẹbi, ki nsọ fun ọ olori *dan* lo jẹ ojẹ olori fun. Ngbọ iwọ ti iwọ fi giri mọkai wipe iwọ ni iriju Baba loni, to mu ile to fi nhaya, ti iwọ nfi girimọkai gbe inu rẹ to si sọ ile yi di ile Dunia ti Baba yi ba gbera nkọ enyin ara mi awọn yoku rẹ wọn ni gba ni owọ rẹ, wọn ko ni ni kọ wa san owo ihaya igbati o ti ngbe inu rẹ, wọn fun o nile o nkun lẹfun ogbọn to ẹniti o kọ bi! Iwọ ha gbagbe wipe Ọba mi yio jẹ ti ko ni mọ Joseph mọ, nitori na ara mi ẹ ji giri, ki ẹsi yi ero inu yin pada, wipe ẹnyin ni lati ni ibugbe kan ni aiye, iyẹn ni ki ẹran ju mọ, ẹma ran ju mọ ile ẹbi, nitori gbogbo rẹ a fọwọ ba fi silẹ ni, ko si eyiti a ma mu lọ ninu rẹ, iwọ ko ni mura ninu ọdun titun ti ao mu yi wipe ki Ọbangiji Ọba ogo, ko ṣe iranwọ fun ọ, bo ti ṣe ma ni ika kan ni aiye, eyiti wọn ma ma pe oruko rẹ mọ ọ lara, eyiti yio ma gbe iyin rẹ ga, abi iwọ ko ni fi eyi sero ni ọdun 1929 to ma mu ni ireni wipe ki Ọlọrun le gbọ adura rẹ, abi ọmọ ẹgbọn ọmọ aburo lo ma ma gbe jọ, lo ma ma gbe pọn bi ọmọ rẹ, jọ ara mi eyiti to gbe pọn yẹn o san fun ọ ko gbe "Ọmọlangi" pọn, ma fi arọ rẹ ṣere, ko ma fi alẹ rẹ ma sare ika kọn kiri, Ọlọrun lo npese ṣugbọn jigiri ni gbesi aiye rẹ yi, Oluwa na yio da ọ lohun, "wọn fun ọ nile on kun lẹfun o gbọn to ẹni to kọ"

## "MA HUWA ANIKANJỌPỌN."

Ọdun keresimesi ijarun ndun fun ọ yungba, oro wipe ko si ẹniti to to ọ, bẹni o dun fun ọ ni eşi bi, bẹ lo dun fun ọ ni idunta, ıwọ ko ha ni fi tọrọ ninu ohun ini rẹ bi? Fun ọdnn 1929 to ma bọsi ni ijọ mẹrin loni ko le jẹ ọdun to ma ṣe anfani tun ọ, wipe iwọ Ọlọrun Ọba ma jẹki ọla mi pọsi ninu ọdun ta ıma bọsi yi—ma jẹ kin jẹ anikanjọpọn ninu ọdun ta ma bọsi, ki lo njẹ anikanjọpnn, oyinbo papa nsọ wipe "Live and let live" wọn ni ki ọwọ wẹ ọwọ ni ọwọ fi mọ, bi ẹnikan ba jẹ ko ma dina fun iyoku, wipe ara-kunrin ıni ko ri iṣẹ ṣe, ki iwọ ma sọpe ko si aye, iwọ fun ni aye ko le ri tirẹ ṣe nibẹ, ki iwọ ma sọ wipe Williams meji ọmọ baba kanna ko le wa ni ofisi kanna, iwọ ko ha ri Cameron meji melo-melo irufẹ bẹ ninu awọn oyinbo, nkan kekeke wọnyi, o ma nbu enia ku ninu igbesi aiye rẹ ni, nitoripe ko yẹ ka di ara wa lẹnu, ninu gbogbo nkan ti iwọ ba nṣe, nitoripe bi iwọ ba ni ni, ko fun ẹnikeji rẹ ni Ọlọrun wi, bi ara rẹ ba wa ninu amudi, maşe ore fun ti iwọ ma fi sọrọ si ni ẹhin ọla, wipe iyẹ bayi ni iwọ na, bo ma ṣe ore fun alamudi ṣe e lalai boju wo ẹhin. "Fi tọrẹ ninu ohun ini rẹ, ma si ṣe yiju rẹ kuro lara talaka kan............Ẹnikẹni ti o ba ni ohun rere aiye yi, ti o si ri arakunrin rẹ ti iṣe alaini, ti o si se ilẹkun iyọnu rẹ mọ, bawo ni ifẹ Ọlọrun ti mba oluwarẹ gbe? Emi fi eyi kọ nyin ni ogbọn nitori pe iwa anikanjọpọn, ifẹra-

ẹni ni kan, ko pe ni aiye yi, nitori pe gbogbo nkan ki lọ bakanna ni igbagbogbo.

Ẹnyin ọkawe wa, ẹ jọwọ ẹ jẹki nji diẹ ninu iwe "Songs of the cell" ti ọwọ Horatio Bottomley eyi ti o wi bayi pe :—

NUNC DIMITTIS.

*On leaving Maidstone Gaol,"*

(JULY 29th 1927.)

Thy servant, Lord, let now depart,
By pen and spoken word
To tell the things mine eyes have seen,
The things mine ears have heard ;
To tell that crime nor sin sahll cease
Until, in face of all,
A new Evangel be proclaimed
To raise up them that fall ;
To be a light to all mankind
Undreamed in ancient story ;
And not alone of Israel
But all thy people's glory.
No soul shall then be cast adrift,
No straying spirit lost ;
And Glory to the Father be,
To Son, and Holy Ghost ;
Three mystic names, whose hidden truth
The world at last shall see,
For God—for Man—for Spirit world ;

IMMORTAL TRINITY.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ENIA KO DA BI ALLAH.

---

## ITORỌ IBUKUN ATI ANU ỌLỌRUN FUN ỌDUN TITUN ATI IRANTI MADAM ODUTẸMINỌWỌ, ỌMỌ ODUTUWA TI IPẸRU IJẸBU RẸMO

Mo juba o, Ẹnyin alagba,

A ki gbogbo nyin pe, ẹ ku ọdun ẹ ku iyedun o, ki Ọlọrun ki o ṣe ọdun yi ni rere fun gbogbo wa ati ibukun rere ati owo rere ati aya rere ati ọkọ rere ati alafia rere fun gbogbo wa, ki Ọlọrun ma jẹki ẹnikẹni ri buburu ninu wa, ki Ọlọrun jọwọ ba wa ti ilẹkun arun ati ilẹkun buburu ki O si jọwọ ṣilẹkun rere fun gbogbo wa. Ki Ọlọrun jọwọ le alakowaba tabi alako ran jina si Ọba wa Alapẹru, ikan ṣoṣo araba nla ọwọkalade O. O. Ọbashibọnoye Ki Ọlọrun jọwọ ma jẹki a ri iku awọn ọdọmọde mọ ninu ọdun yi ati lailai, amin.

Ni iranti Madam Odutẹminọwọ, ọmọ Odutuwa ti o ku ninu ọdun 1912, o jẹ ọkan ninu awọn enia pataki ni Ipẹru ki Ọlọrun jọwọ ba wa toju awọn ọmọ rẹ ati awọn ẹbi rẹ tabi obi rẹ gbogbo ti o fisilẹ lọ, ki Ọlọrun jowọ ba wa pa aṣiṣe rẹ rẹ, amin.

Awọn ara Ipẹru nkọ orin kan ni ọdun 1915, wipe aperun-pẹlọtan ara bẹni aye ọta mi o, aperun-pẹlọtan he e onişegun to ba pa wa korowo jẹun 3. Ẹjọwọ ẹ lọ ka iwe awọn Onidajọ ori 16 ẹsẹ 28.

Emi ni tiyin nitotọ,
J. A. O. SHOMADE.

---

## IṢẸ IYANU YORUBA.

Olori Aje ti a mọ ti ko si wọpọ ni igba atijọ ni Aje Irawọ, eyiti bi ọran ko ba di ọran iku tan a ki ifi ọran ẹni lọ. Ohun pataki ti ima mu awọn enia lọ fi ọran wọn lọ ọ ni pe bi a ba pe wọn li oṣo tabi ajẹ. Nigbati ẹni meji ba nja ija irira, ti ekini ba pe ekeji rẹ ni ajẹ ni ipe ododo, (o jasi ọran iku fun ẹnikẹni ti o ba ni ajẹ nigbani, ko jọ aiye isisiyi ti ọpọlọpọ nfi ẹiyẹ-nini ṣe ohun iyi), bi o ba da ẹniti a pe li ajẹ loju pe on ki ṣe ajẹ, a mu igbiwo owo okun ti ki ṣe ejidigba, a si di mọ ori ara rẹ, a si ma kigbe yi ilu ka bayi pe :—

"Bi mo ba n'ajẹ
Ori mi di ori Polo ;
Bi nko ba n'aje,
Ori mi di ori Oṣo."

Eyi ekeji to pe e ajẹ to si ntẹnumọ pe ajẹ ni işe a si bọ si ode bakanna, ti on ti iye owo kanna lori rẹ, a si ma wipe :—

"Bi mo ba purọ
Ori mi d'ori Polo ;
Bi nko ba purọ,
Ori mi d'ori Oṣo."

Bayi li awon mejeji yio ma ṣe yi ilu ka li orowurọ fun ijọ meje, ohun ti nwọn nṣe yi ni nwọn ima pe ni "ikeri irawọ," nwọn a si ma wipe awọn mejeji "keri Irawọ," ; eyini ni pe nwọn fi ọran wọn lọ Aje ti mbẹ ni ilu Irawọ. (Ṣaki ni ilu ti nje Irawọ ni lailai). Ki ijọ meje ikeri Irawọ yi to kọja, gbogbo agbagba ilu, enia agbo-ile, ati ojulumọ yio ma gbidanwo lati le pari ija yi fun wọn, bi nwọn ba si le ṣe e yọri titi ijọ meje yi yio fi pari, gbogbo agbajọ ilu a pejọ, nwọn a si pe awọn mejeji lati gbọ idi ẹjọ li ẹnu wọn, lẹhin eyi nwọn a si fi aişemẹlẹ wadi ọran na titi oṣu mẹta, lẹhin na ni nwọn ito wa da ẹbi fun ẹniti o da wọn loju pe o jẹbi, nwọn a si fi are fun alare. Ṣugbọn nigbati ẹniti a dalẹbi ko ba ni itẹlọrun si idajọ ti gbogbo ilu ṣe fun u, amọbi lilọ ni nwọn o lọ si Irawọ dandan. Awọn agba ilu a si yan onişẹ tẹle wọn lati mu wọn lọ sọdọ Ajoriwẹn ti işe Ọba Irawọ.

Nigbati gbogbo nkan ba şe tan, awọn agba ilu a bere igba-ademu kọkan lọwọ awọn mejeji, nwọn a wipe, Ọba tabi balẹ ilu fẹ fi di ẹru şọwọ si Ọba Irawọ. Ninu ẹru yi ni iku ati iye wa fun ẹniti o ru u; şugbọn ọrọn awo ni igba lailai, o si jẹ ohun ti o han fun Ọba ati awọn iwarẹfa ilu nikan, ko si ẹnikẹni ninu awọn to mọ awo na to si gbọdọ ya a si ita. Ọşẹ, osun ati ẹfun ni ohun ti nwọn nfi sinu igba ti ẹniti gbogbo ilu ti dare fun, kiki edu ni nwọn si nfi kun inu igba ti ẹlẹbi, nwọn a si kun ẹhin igba mejeji na li ẹfun ki nwọn le farahan bakanna li ode, nwọn a si gbe ti olukuluku fun u. Awọn ẹniti ima ba wọn lọ si Irawọ ni awọn ibatan wọn timọtimọ meji-meji tabi mẹta-mẹta, ati awọn onişẹ ti ilu ba yan. Li ọjọ ti nwọn ba ti jade ni ilu ni ọfọ ti şẹ Ọba ati idile awọn ẹlẹjọ mejeji. Ọba a ma şọfọ nitori awọn to lọ ko gbọdọ bọ wa ba a lori itẹ, nitori Ofin daindain ni pe Ọba ti nwọn ba ti oju rẹ lọ si Irawọ ko gbọdọ şe aima wọ aja ki nwọn to de; awọn ibatan awọn ẹlẹjọ a si ma şọfọ pẹlu nitori pe ominu nkọ wọn nitori nwọn ko ti mọ ẹniti yio yege bọ Irawọ. Nigbati nwọn ba de ibode Irawọ, onibode a da wọn duro, a si ranşẹ lọ sọ fun Ọba niti iru alejo ti nbọ wa sọdọ rẹ, Ọba a si ti palẹmọ lati gba wọn; a si ranşẹ lati mu wọn wa si afin, nibiti yio fi wọn wọ si ọna marun wọnyi:—a fi awọn ẹlẹjọ ekini ati ekeji wọ si igun ekini ati ekeji ile, awọn ibatan si igun ẹketa ati ẹkẹrin ile, awọn onişẹ Ọba si ọdọ Ọtun Iwẹfa. Li ọjọ keji nigbati awọn Iwẹfa mẹfa ba joko ti Ọba, aborẹ Polo ti o ti igbo Orişa-oko de ki ilẹ to mọ a joko sunmọ ibẹ pẹlu; nigbana ni awọn ẹlẹjọ mejeji iwa fi igba wọn jişẹ fun Onirawọ loju gbogbo enia. Li ọjọ ti Ọba ba da fun gbigbọ ẹjọ wọn, gbogbo agba ilu a pejọ, nwọn a si da ẹjọ gẹgẹ bi ọgbọn inu wọn ba ti ri. Nigbayi ni Ọba yio to lọ şi igba wẹn wo; bi idajọ na ba ti ri bakanna, nwọn a dẹbi fun ẹlẹbi ati are fun alare; şugbọn bi idajọ na ba yato Onirawọ a wipe ẹjọ sun. Li ọjọ ti a o ba tun pe ẹjọ na, awọn onidajọ miran ni gbọ ọ ti isi dajọ: bayi ni nwọn isi ma parọ onidajọ titi idajọ wọn yio fi ri gẹgẹ bi iwe ti a ti kọ sinu igba wọnni. Awọn Iwarẹfa mẹfa-mẹfa ni ima da si ẹjọ Ọba Irawọ, ipo wọn si dabi ti awọn juri ti nran onidajọ lọwọ ni ibi idajọ ti Ọba Gẹsi; nigbati awọn mẹfẹfa ba si ti fohun şọkan da are tabi ẹbi, ọrọ ti nwọn ba sọ abẹ lo ke e. Şugbọn bi ẹlẹbi ba nkọ sibẹsibẹ, Onirawọ a da ọjọ ti on yio mu wọn lọ fọju kan Polo. Fun ijọ meje ni ilu yio ma şe kikankikan ni igbo Orişa-oko, nibiti Polo yio ma jade jo li orọ ati li alẹ bi egungun şugbọn aşalẹ ijọ keje ni ọjọ ati pari ọran awọn ẹlẹjọ meji wọnyi. Bi nwọn si ti dọbalẹ ni idojubolẹ buruburu larin ago ti ilu Polo ndun kikankikan bayi pe:—

"Polo pa, Polo jọwọ rẹ;
Polo pa, Polo jọwọ rẹ."

Polo a yọ jade lojiji si ibi ti nwọn dọbalẹ, a si fi ẹfun ati osun gun alare, şugbọn a fi ọmọ-owu fọ ẹlẹbi lori, lojukanna agbo a tuka awọn olorişa-oko Irawọ a si gbe ẹniti o yeje wọ inu igbo lọ şe Orişa-oko fun u; lẹhin ti gbogbo opo na ba pari, nwọn a fun ni ọpa Orişa-oko (ọpa irin kan bi iwọn ẹsẹ meje,) ati igba ẹfun, ati ọbẹ idẹ kekere kan fun ati ma kọ ẹfun na sori tirẹ ati sori ẹnikkẹni ti a o ba ti ọwọ rẹ gba si inu Ẹgbẹ olorişa-oko. Pẹlu ọpọ ayọ ni on ati awọn enia yio ma fi bọ wa ile, ihin yio ti şaju rẹ de ile ọpọ enia isi wa pade rẹ: şugbọn itiju ati ẹgan de si awọn ti enia wọn kuje ti aiye. Bayi ni o ri nigba atijọ ti enia ifi di olorişa-oko, ti nwọn si ima jẹ orukọ mọ ọşo tabi ẹfun.

---

## IWA AGABA-GEBE AWỌN ỌMỌ ANABI ADAMỌ.

(APA KETA)

---

## IWA AGABA-GEBE AWỌN ỌMỌ ANABI ADAMỌ.

O mbẹ ninu ọpọlọpọ ninu awọn ẹda ti o jẹ oniwa buruku enia, ẹwẹ ti nwọn si jẹ onisọkusọ ti ma nsọ ọrọ buruku jade lẹnu nipa işẹ buburu ti nwọn nşe, irufẹ ti o le mu ọkan awọn ẹlomiran duro nigbati nwọn ba ngbọ ọrọ buruku ti o nti ẹnu wọn jade, awọn ẹniti ti a le pe ni omugọ ati ogunran enia.

Lai ni tabi a ti mọ wipe ina ti a nri ka ninu ọrọ Oluwa nipa ohun ti Oluwa fẹ ati nipa ohun ti Oluwa ko fẹ, dajudaju enia ni Ọlorun yio fi si inu rẹ nipa awọn ẹniti o ba tẹ ofin Rẹ leti, bẹni a si ni igbagbọ wipe ẹniti o ba pa ofin Rẹ mọ ni yio jẹki o le wọ Ijọba ọrun nibiti awọn Imale npe ni Alijọnna.

Şugbọn a ko le fe awọn eşu ti ẹda ku bi a ko tilẹ le ri eşu papa ti Oluwa fi ma şe ẹda rẹ, awọn eşu enia bẹ si ni lati wa ẹniti yio ba wọn wọ ibiti nwọn gbe nlọ, iyẹn ni nwọn fi ma npa ni owe pe "Ajegbodo wa ẹni re kun 'ra".

Bi ẹnikan ba mbẹ nisisiyi ti o nhuwa ti ko dara, ti o si mọ gbangba wipe iwa ti on nhu na ni lati jẹ on niya, ko ni fẹ ki iya na jẹ ti on nikan şoşo, yio tun ma wa ọrẹ kun ọrẹ ni lati le jẹki o ba on tọ iya na wo, Ọlọrun ki o ma fi wa fun eşu enia ati ti Bilisi mu, eşu enia ati ti ọrun-apandi ẹgbẹra ni wọn, nitori iru işẹ kanna ni nwọn nşe.

Nipa eyi ti mo nsọ bọ wayi, ko yẹ ki a ma lu lagbegbe awọn ẹniti o ba ti mura wọn ni ọrẹ eşu ti a si ti fi oju ara wa şun gẹgẹbi iwa wọn, nitori kini o? Nitori ọjọ ti iya wọn ba ma de, ki ẹlomiran ma ba fi ara gba ninu rẹ.

Ẹ ko ri wipe iwa ti ẹlomiran nhu lode ti a wa yi, o ju ti Abilisi pa lọ, ẹniti o ti ṣe ileri pẹ on yio ba awọn ọmọ Anabi Adamọ ṣe ninu Duniyan, ki on ba le ri ẹni pẹlu on lọ si inu ina orun apandi. Ki lo mu ija ṣelẹ ki Ọlọrun to ṣe ibi le Eṣu lori? Nitoripe Ọlọrun ni ki o lọ sujudu fun Adam ṣugbati Ọlọrun da a gbara, ṣugbọn Eṣu ni agbẹdọ ki itun nṣe on ni yio tun ko bẹrẹ fun Adam, nitoripe iyẹpẹ ni Ọlọrun fi da a, ina si ni Ọlọrun fi da on, bẹni Eṣu kọ patapata, ọran ko ju bẹ lọ, ki Ọlọrun maṣe jẹ a ko si inu pakute eṣu ọmọ Anabi Adamọ ati Abili.

A de ibiti a nlọ mo fẹ bi wa lere, opolopo enia lo ngbọ ede ti nwọn npe ni Agabagebe ṣugbọn ko ye won te, ki lo njẹ Agabagebe? ngo si la han nyin nisisiyi.

A gbọ wipe Anabi Yisa ati Anabi Momodu kọ iwe Agabagegbe eyiti a wa mọ si "Abosi" ni ede Oyinbo o njẹ "Hypocricy", Sugbon itumọ rẹ pe igba, on kanna no a le pe ni ṣoke-ṣode, rikiṣi munafiki, monani, ati bẹbẹ, iwọnyi ti a darukọ yi ede kanna.

Ni ọsẹ te nbọ ni a o bẹrẹsi ṣi fafa ọrọ na lagbara Ọlọrun.

(*Koi pari*).

ỌMỌ-ILU.

---

## IMALE KINLA!

Anu ṣe wa pupọ lati ma ri aṣa kan ni airin awọn Imale miran, irufẹ aṣa bẹ si jẹ ohun ti o ku diẹ ki o to loju wa, nitori nwọn ma npa owe kan pe itiju pa ini arẹ epe, nitorina li a to n ṣe fẹ ṣe ikilọ fun irufẹ awọn Imale ti nwọn ma nsaba ṣe bẹ.

Aṣa na ni wipe bi awon Imale miran ba lo ṣe okankan lode bi suna, yio t bi ohun miran ti won ba si bun wọn ni sara owo ta n ohun jijẹ bo tanran ki nwọn wa si ile, ki won si pin n an na letoleto larin ara wọn, nibti ọkan nfẹ mu ju okan lo, ija a de, ariwo a wọ ọ, yio di ak t kiti tobẹ ti gbogbo ẹnikẹni a fi mọ wipe awọn Imale lọ si ibi sara kan, ti nwọn a si ma fi wọn ṣe yẹyẹ.

Ahlikuwa bi o si wa di ohun ti nwon nja si yi boya lo to idamẹwa ohun ti Ọlọrun ṣe fun ẹl miran ni toro iyara re, ti nwọn a si ti itori re ma pa ariwo le ara wọn lori ni gban bi. Ki awon ẹniti o ma nsaba ṣe bayi ẹ jẹ ki a ronu daradara pe isin Anabi Momọdu (ikẹ ati igẹ Olọrun ki o ma ba a) ki iṣe isin gẹgẹ bi ẹlomiran ti mọ o si.

Nipa ṣiṣe bayi awon ẹlẹsin miran ma nfi wọn ṣe yẹyẹ ni, o si ni gbọ nkan meji lenu wọn, bikoṣe awon Imale de o, nwọn ri ibi sara kan lọ, yẹyẹ patapata gba li eyi jẹ, ẹ gba ọran yi yẹwo. Asalatu fun Anabi.

MUSULUMI-ODODO.

## IKU O!

Anu ṣe ni lọpọlọpọ lati gbọ iku arakunrin wa Yesufu A. Pedro to ṣelẹ ni Pedro's Compound Oko-awo, ni ọjọ *Thursday* to koja—A ba ẹgbọn rẹ Khamast A. Pedro kẹdun gidigidi fun ajalu nla na, ki Oluwa fọrijin ati baba wọn Ashiru Pedro (Trader) ti Portonovo market Street, Lagos—Ẹni ti o fi ilẹ bora ni ọjọ *Wednesday 7/4/26.*

"Erupẹ sa ni awa, awa yio si pada di erupẹ."

---

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi", jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Origi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnvin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, DECEMBER 29, 1928.

## ỌDUN GBẸIYẸFO NRE 'BI ANA.

Ki a to ri ọjọ mẹta kan si Ọdun 1928 ti a mọ bi ọdun gbẹiyẹfo (*Leap year*) yio di gbigbe sin gẹgẹbi awọn ọdun aṣaju rẹ. o jẹ igbagbọ ọpọlọpọ enia ni lailai pe ọdun aluba ni ọdun ti a npe ni ọdun gbẹiyẹfo jẹ, ati pe ohun buburu bi arun iku ojiji ati orişirişi nkan *asaba* ki ṣa lai nwa ninu ọdun gbẹiyẹfo. Loju wa ati gẹgẹbi gbogbo nkan ti nlọ si a ko ro pe kosi ọla ninu oje nitipe ọdun kan dara ọdun kan ko dara: a şebi gbogbo wa ni a ti rekọja ninu ọdun 1927, tani ko mọ bi nkan ti le to ti owo kosi ti òwó kosi ti ofin miran ndamu ilu, ẹnikẹni ti o ba şakiyesi rẹ ti o si dẹju ki o ri imu yio ri pe yiyipada biri ti gbogbo nkan yi pada bayi bẹrẹ ni ọdun 1923 tabi 1924 eyini ni lẹhin igbati aiye owo *Currency* ti lọ, eyiti o gbera diẹdiẹ ni ọdun 1918 lẹhin igbati nwọn sọpe ogun pari. Şiwaju ọdun 1918 şaşa enia ni ibi tabi ni ilu ibomiran ni nkan ko şe gbẹdẹ fun: a ri ninu awọn onişowo ti £1000 ki şarẹ rẹ lati ko da silẹ lẹsẹkẹsẹ lalu ranşẹ lọ si Banki; nkan yi nlọ bayi ki o to yi biri ti o si bẹrẹ si sojude lati ọdun 1924, titi o fi sojude patapata ni ọdun 1925 titi di oni. Lati igbati oşu *December* ọdunni ti le ni a ri ti Eko ntu yẹyẹ ti awọn enia nlọ ti nwọn si mbọ fun ipalẹmọ ọdun miran şugbọn alejo lati ilu okere lo papọju ninu awọn ero wọnyi; ti a ba tilẹ wo awọn ti nwọn nşe ọdun ilẹ yi a o ri pe owọ awọn alejo lo tun şubu si; Egungun Sẹkiri ti o njo kakiri igboro ni iwọ yio wipe ere Eko ni, tabi Egungun Kurumọ ti o dudu fafa bi ẽdu ti o si nsa jiajia kakiri opopo ode ni iwọ yio pe ni ere Eko: nitotọ gbogbo enia kọ ni igba yi le fun; ko le fun awọn ti nwọn ntẹwọ gbowo ile meji mẹta tabi ile ti o ju bayi lọ loşoşu, ko le fun awọn ti nkan kan oko wọn lododun bi *Cocoa* ko ja ri ti nwọn si ni ọpọlọpọ nkan Ọgbin miran; biotilẹjẹpe awọn enia wọnyi le ni inawo wọn sibẹsibẹ ati dajudaju awọn atọju ile ko le fi ara we awọn enia wọnyi. Bi a ba ma sọ wipe bi nkan ti lọ si lọdun ni a o sọ pe iku pọ gẹgẹbi o ti pọ lẹşi, arun si pọ bakanna, iku ẹgbako si pọ bakanna gẹgẹbi ti ọdun miran, nitorina diẹ lo yẹ ki ẹnikẹni ma sọ ni ti pe ọdun *Leap Year* ki şe ọdun rere: ọda ti o de yi kan aimọye enia, melo ni a le mọ ninu awọn ẹlomiran ti nwọn ti fi oru boju fẹhinsilẹ kuro ni ilu tabi melo ni ẹnikan le mọ ninu awọn ti nwọn ti nro-dẹdẹ ti nwọn si ti ngba-dẹdẹ nipa alafia ati owo ti o mbẹ fun wọn ti nwọn si wa ni ipo miran lode oni o jẹ aşa ọmọ-araiye lati ma gbayĩn ni ile ẹniti nkan ba şenure fun şugbọn iwọ jẹ ki ọsa d'odi fun irufẹ ẹni bayi na ki ogun Ọba d'atunro nigbana ni iwọ yio ri sisesẹ ti nwọn yio sesẹ ni odo rẹ. bẹni ti aiye ri, Aiye Akamara !!!

Ni akoko diẹ ti ọdun titun ọdun 1929 ma yi wọle de ẹ jẹ ki a gbadura ki a si bẹbẹ ki Olodumare maşai şe ọdun na ni ọdun REMILEKUN fun olukuluku wa, ki Baba ti o ri inu ẹdun olukuluku maşai jọwọ ki O si dakun şilẹkun Owo anfani fun temi tirẹ ki o si maşe huwa si wa bi ẹşẹ wa, Amin ki Ọdun 1929 jẹ ọdun Owo ọdun ọmọ. Aşẹ.

Aşẹ t' Edumare.

## EJUGBAGBE.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji,

Ko si aşanu tobẹ ninu işẹ ti a o şe loni nipa awọn ohun pataki ti o şẹlẹ fun ọdun yi.

Ohun ti a kọko fẹ bere na ni wipe kilo njẹ "Ejugbagbe" gẹgẹbi ohun ti a wa loke yi? Daudaju şaşa ẹniti ko mọ wipe ohun ti ko ya gbagbe lo njẹ bẹ.

Nitori ohun pataki ti ki işe eyiti enia le yara gbagbe ti o poju loju wa nipa ohun ti o şẹ larin ọdun lo ti jẹki a ranti orukọ yi, şugbọn eyi ki işe

ohun ti a le so loni, a fę fa iwaju lọ na, ki a to fi abọ wa ba ipakọ.

Iwaju ni eyiti ao bẹrẹ loni yi, lẹhin iyẹn ni ao to ṣe ara wa ni iranti awọn ohun eyiti a ka si "Ejugbagbe"—iyẹn ni ipakọ.

## AWỌN OHUN PATAKI TO ṢẸLẸ NINU ỌDUN 1928.

1. Awọn Oyinbo mẹta yi Ogagun Walter Elliolt, M.P., Ogbẹni William Bunn ati Ọgbẹni G. Morgan Garro-Jones de si ilẹ yi lọjọ 6 oṣu yi lati ilu Oyinbo.

2. Olọla Gomina Graeme Thomson ati Aya rẹ ṣe Awowo (At Home) ni ile Gomina L'Ẹhingbẹti ni ọjọ 7 January 1928.

3. Ẹni-ọwọ James Emanuel Wright ṣe alaisi ni ọjọ 7 January 1918.

4. Nwọn pade ẹjọ Arotunro (Apeal) ti Akilolu Akodu pe Yesufu Omidiji, Lemọmu Kasunmu Olokodana, Akinsanya Mọgaji ati Bakare Oṣẹru niwaju Onidajọ M. L. Tew ati Maxwell ni ọjọ 11 Jauuary 1928: Akilolu Akodu jẹbi.

5. Awọn Olotu Ẹgbẹ Dẹmọ fi awọn ẹni wọnyi si ipo lọjọ 12 January 1928 ni Ajọ Igbimọ won ni Ile-Afari-Ogun:—Dokita J. A. Caulcrick, Ọlọla Loya Eric O. Moore Loya T. A. Adebayọ Doherty, Loya Isaac Kuṣika Robert, Ọgbẹni Thomas H. Jackson, Ẹni-ọwọ J. R. Williams, I. Ibaru, George, I. Phillps, Phillips Williams F. G. R. Leigh, A. O. Cole James Bailey, Lemọmu Lawani, Musa Başọrun, Lemọmu Ọba (Okunnu) Ọlọla Dokita Jones, Herbert Macaulay ati Bagan Benjamin.

6. Awọn ẹgbẹ Dẹmọ ṣe Ipade Gbogbo-gbo ni ọjọ 14 anuary ni abẹ Alaga Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones ni ile Afari-Ogun "Glover Memorial Hall) Ẹhingbẹti, ninu ipape yi ni nwọn ṣe ṣawura lati ṣe iwe-ẹbẹ (Petition si Secretary of State) nipa Owo-ori.

7. Ọmọge Paul Aina ọmọ Ọgbẹni Herbert Macaulay ṣe alaisi ni ọjọ 7 January 1928.

8. Awọn Oyinbo Ọgagun Walter Elliolt, M.P., Ogbẹni G. Morgan Garro M.P., kuro nihin lọ si ile lọjọ 10 February 1928.

9. Awọn Musulumi mu awẹ ni ilẹ yi lọjọ 22 February 1928.

10. Dokita John Randle jẹ alaisi ni ọjọ 27 February 1928.

11. Awọn Musulumi Kirun ọdun "Edil-Fitri" ọdun Kekere ni ọjọ 23 oṣu March 1928.

12. Ọgbẹni Josiah Henryson Doherty ṣe alaisi ni ọjọ 24 oṣu March 1928.

13. Jamat Musulumi-ilu (The Central Mosque) lọ ki Oyinbo Ọgagun Willimas Birrell Gray fun ayọ ọdun ni ọjọ 30 March 1928.

14. Awọn Kiriyo ṣe ọdun ọjọ Ajinde Kiristi (Easter Sunday ni ọjọ oṣu April 1928.

15. Ọkọ Jomi-joke ti Oyinbo Alan Cobham de si ilẹ yi lọjọ 11 April 1928: Ọkọ na kuro nihin ni lọjọ 15 April 1928.

16. Ẹni-ọwọ Simion Peter Johnson jẹ alaisi ni ọjọ 16 April 1928.

17. Nwọn ṣe ẹjọ Arotunro ti Ọmọba Eṣugbayi Eleko ni ilu Oyinbo (Privy Council) ni ọjọ 30 April ati 1 May 1928.

18. Oloye Ọbanikoro (Adamọ Akẹju) ati awọn isangbe rẹ rin irin-ajo lọ si Ibadan ati Ọyọ ni ọjọ 5 May 1928, nwọn si pada de ni ọjọ 9 May 1928.

19. Awọn Musulumi Kirun "Eidil-Azuah" ọdun nla tabi ọdun Ileya ni ọjọ 30 May 1928.

20. Ọgbẹni Thomas Bankọle Bukọ (Asst Chief Registar) Akọwe Kotu bẹrẹ isinmi ni ọjọ 30 June 1928, fun oṣu mẹta, lẹhin eyi ti o si di ẹni ifẹhinti fun iṣẹ rẹ.

21. Ina jo ni Oke-Arin ni ọjọ 1 oṣu June 1928, ninu eyiti enia mẹjọ ṣofo ẹmi si inu rẹ.

22. Ogbẹni John Buxtulph Didorus Johnson, ti nwọn npe ni Gbengbeleku jẹ alaisi ni ọjọ 16 June 1928.

23. Ọmọba Esugbayi Eleko jare ẹjọ Arotunro rẹ ni ilu Oyinbo Prifi Kansulu ni ọjọ 19 June 1928—idajọ awọn Onidajọ Ogunnagbogbo ti o joko lori itẹ ni wọnyi:—Lord Buckmaster, Lord Warrington ati Lord Chancellor ẹniti o ka idajọna.

24. Awọn Ọmọba ile Dosunmu ati Ọmọba Eṣugbayi Eleko yọ ọwọ Loya Jonathan Collins Zizer kuro ninu ẹjọ Eleko na lati ojọ 20 June 1928, gẹgẹbi iwe-irohin *Lagos Daily News* ọjọ 29 June 1928 ti wi.

## THE HOUSE OF DOCEMO.

We have been authorised to state that the members of the House of Docemo have withdrawn from Jonathan Collins Zizer, Esquire, Solicitor of the Supereme Court of Nigeria, their instruction, empowering him to act a Solicitor in the Eleko Case; and that such withdrawal has been confirmed by Prince Eshugbayi Eleko at Ọyọ on 20th instant—*L.D.N.*—27/6/28.

25. Lemọmu Mọmọdu Dabiri ṣe alaisi ni ọjọ 3 July 1928.

26. Nwọn bẹrẹ si ẹjọ ti awọn Olopa pe Oniwe-irohin *Lagos Daily News* J. A. Olushola ni iwaju Adajọ H. A. Young ni ọjọ 6 oṣu June 1928, nipa Agbọsọ ọran Ọtẹ ẹtu-iọn o ti jade ninu iwe-irohin na ni ọjọ 29 June 1928.

27. Ọmọba David Ọmọyẹle Dosunmu ṣe alaisi ni ọjọ 21 oṣu July 1928.

28. Ibikunle Akitoye ti o jẹ Olori ile Addo jalaisi ni ọjọ 26 July 1928, nwọn sin oku rẹ ni ọjọ 27 July 1928.

29. Onidajọ H. A. Young dajọ fun J. A. Oluṣọla Oniwe-irohin *Lagos Daily News* ni ọjọ 30 July 1928 pe ki o san adọta ponwun bibẹkọ ẹwọn oṣu mẹta fun ẹsun ti awọn Ọlọpa fi sun nipa Agbọsọ ọran Otẹ-ibọn ti o jade ninu iwe-irohin na ti ọjọ 29 June 1928.

30. Bakare Kandu ku lọjọ 4 August 1928.

31. Lazaro Burges da Silva ( Yoyo Ararọmi ) ku lọjọ 7 August 1928.

32. Ajali Adamọ ṣe alaisi ni ọjọ 8 oṣu August 1928.

33. Sumọnu Atiko ṣe alaisi ni ọjọ 9 oṣu August 1928.

Oyinbo Alagba Samuel Wilson K.C.B., K.C. M.G., K.B.E., ati aya rẹ de si ilẹ yi ni ọjọ August 1928.

34. Oyinbo Alagba Samuel Wilson K C B. lo bẹ Mọṣalaṣi Jimọ (The Central Mosque) wo ni ọjọ 18 August 1928, Lemọmu-ilu (Mọmọdu Ligali) ati awọn Ratibi gbobgo pẹlu awọn Jamat ki Oyinbo na lọjọ na.

35. Lord Viscount Haldane F.R.S., K.T., O.M., ti ilu Oyinbo ṣe alaisi ni ọjọ 19 oṣu August 1928.

36. Ọgbẹni Herbert Macaulay ati Dokita John Akilade Caulcrick ti nṣe Olotu iwe-irohin *Lagos Daily News* lọ jẹjọ ti awọn Ọlọpa pe wọn ni iwaju Onidajọ H. A. Young ni ọjọ 23 August 1928: Nipa Agbọsọ ọran Otẹ ẹtu-ibọn ti o jade ninu iwe-irohin na.

37. Sanusi Olusi jẹ Oye Ọba of Lagos ni ọjọ 24 August 1928.

38. Awọn Musulumi ti Eko ṣe ayọ odun Ọjọ-ibi Anabi Mọmọdu ni ọjọ 27 August 1928.

39. Onidajọ H. A. Young da Ọgbẹni Herbert Macaulay lẹbi ni ọjọ 27 August 1928, pe ki o lo si ẹwọn oṣu mẹfa ki Dokita John Akilade Caulcrick san adọta ponwun tabi ki o lo si ẹwọn oṣu mẹta nipa ọran Agbọsọ Ote ẹtu-ibọn ti o jade ninu iwe irohin *Lagos Daily News* na.

40. Iwe-irohin Ijọba (*Gazette*) ti ọjọ 30 August 1928 da Dokita John Akilade Caulcrick duro ninu Aṣoju mẹta Eko ni Igbimọ-Aṣofin (Legislative Council) nipa idajọ ti Kotu da a ni 27 August 1928.

(*Koi ti pari.*)

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

# *Olusakin's Column.*

ARRIVAL.

We welcome Prince E. A. Adeyemi of Ifẹ who arrived Lagos from Ile Ife on Monday, the 24th December 1928, to witness the Lagos Races.

He resides at Mr. Adeshigbins "Bamidupẹ's" House, 60, Apapa Road, Ebute Metta.

THE ARCHDEACON OF LAGOS.

The Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, L.Th., left Lagos on Christmas Day, the 25th December, for Oke Ọdan on special engagement.

ANOTHER ASPIRIN DEATH.

At an inquest last week on William Hettin, who it was stated died from aspirin poisoning, the Acton Coroner observed that there was much ignorance regarding this dangerous drug. The Ministry of Health knows all about the danger—we have told them. When are they going to act?—*John Blunt*, 1/12/28.

JUDICIAL JUGGLING.

Summing up in a divorce suit the other day, Mr. Justice Hill told the jury that it was "no use awarding an extravagant sum which the co-respondent would not pay." Then, in answer to the natural question put to him by the jury, as to whether they could have evidence of means, he said: "The means and position of the co-respondent did not matter!" The two statements quoted do not appear to blend.—*John Blunt*, 24/11/24.

DEPARTURES.

By the Steamer *R.M.S. Appam* which sailed this port on Friday the 21st December, 1928, Sir R. M. Combe, KT., Chief Justice, and Mr. H. A. Young, K.C., Police Magistrate, were among the passengers for Liverpool, *on Voyage.*

THE ARCHBISHOP OF CANTERBURY.

London, Monday.

The Archbishop of Canterbury is suffering from internal inflammation in the region of the liver. He is staying in bed for some days.—*Reuter.*

OLUṢAKIN.

## ORI V.

## IGBOIYA.

*(Translated from "Character by Dr Smiles").*

APA KARUN.

A ko pa Martin Luther nitori ti ọna ẹsin ti o ntọ; ṣugbọn lati ọjọ ti o ti kọ ti Pope ni ẹmi rẹ ko ti to ra lowo kan. A lẹrọ le sọpe on nikan ati eti rẹ ni, nigbati o kọkọ bẹrẹ iṣẹ nla rẹ. Idiwọ nlanla ni o ri. On na papa sọpe, "Lapakan a ri imọ, ọgbọn, ọpọ enia, ọla, ipo, agbara, ọwọ iṣẹ ivanu; lapa-keji a ri Wycliff, Lorenzo Valla, Augustine ati Luther—ẹniti ko jamọ nkan, ẹni ara ode yi, ti o da duro on nikanṣoṣo afi awọn enia diẹ ti o pẹlu rẹ." Nigbati Ọba ni ki o wa si Worms ki o wa jẹ ẹjọ ti nwọn nba ro pe o nṣe aladamọ, ọ ni ọpa bi on ko ni lọ sọ tẹnu on. Awọn ọrẹ rẹ sọ fun pe bi o ba lọ ko nibọ nwọn yio pa a, nwọn si rọ ọ pe ki o salọ. O ni, "Ewọ, ngo lọ ni, bi awọn eṣu lọrun apadi kunbẹ bi wọbu ti mo nlọ ba!" Nigbati nwọn sọ fun ki o ṣe mẹlọ-mẹlọ nitori ti ẹnikan ti o njẹ Duke George ti o nṣe abinuku rẹ, o ni, "Ki Duke George di ojo ki o ma rọ tọsan-toru fun ọjọ mẹsan ko ma da, emi yio lọ sibẹ."

Bi Luther ti wi, bẹ lo ṣe; o mu ọna pọn. Nigbati o ku sata ibẹ, ti o nwo ile-ẹṣọ alagogo ti ilu Worms lokere, o naro ninu kẹkẹ rẹ o si kọ Orin *Ein feste Bur ist unser Gott*—(Orin Marseillaise ti Reformation)—a gbọ pe gbogbo rẹ ko ju ọjọ meji lọ ti o fi ro Ọrọ Orin na ati ohun ti a fi nkọ. Kete ti ipade *Diet* to jọ, agba jagun-jagun, George Freundesberg, fọwọ le Luther lejika, o sọ fun pe: "Alufa alufa, agbalagba ma dọwọ rẹ; ogun ti o nlọ ja yi ju eyiti ẹnikẹni ninu wa ti ja lọ." Ṣugbọn iba esi ti Luther fun alagba yi ni pe on fi "Ọkan tẹ Bibeli ati otitọ inu".

Iwe ẹjọ ti Luther ro. tigboya-tigboya niwaju Igbimọ (Diet) ọkan l'oko ninu iwe itan. Nigbati Ọba wa pada rọ ọ pe ki o tuba, o sọ pọun, o ni: "Kabiyesi, a ṣebi mo ba ri i ninu Iwe Mimọ tabi ti nba ri i gbangba pe mo ṣina, emi ko le tuba, nko si ni tuba, nitori ko tọ ki enia ṣe ohun ti o lodi si eyiti ọkan rẹ jẹ ẹ leri pe o tọna. Bi igbagbọ mi ti ri nun, ki o ma si ṣe ro pe mo jẹ mu omiran ṣe, Lori eyi ni mo duro: Emi ko le ṣe omiran: Ki Ọlọrun ran mi lọwọ!" O ni lati ṣe ẹtọ—o ni lati gba ti Ẹniti o ju gbogbo Ọba aiye lọ: O si gbe iku ta o ṣe bọ. Lẹhin eyi nigbati awọn ọta rẹ do ti i gba-gba ni Augsburg, Luther ni "bi on ni ẹdẹgbẹta ori lọrun on, on ko kọ ki nwọn bẹ gbogbo wọn sọnu bi o kanran ki on ṣẹ ijẹwọ igbagbọ on." Gẹgẹ bi i ti ri fun awọn enia ti o ni igboya, o dabi ẹnipe bi iṣoro ti o nri ti o si nkapa ti pọ to bẹni agbara rẹ npọ si i. Hutten ni "Ko si ẹnikan ni *Germany* ti ko pe iku ni nkan bi Luther." Nitori o duro lori otọ laifoya, ni olukuluku enia laiye isisiyi fi ni anfani a tilẹ sọ tinu rẹ jade laifoiya, eyi ni o si fi han ni gbangba pe Ọlọrun ko fun enia ni oye lasan: ko si daju pe a ri ẹnikan ti o ṣe to ti Luther.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌBA

---

### CHRISTMAS AT BUCKINGHAM PALACE.

**Royal Family Had Quiet Time.**

London, Wednesday.

The Royal Family spent a quiet and happy Christmas together. The Queen and her five children attended service at the Palace Chapel in the morning. The great occasion was the family reunion at the Christmas dinner table at which Sir Stanley Hewitt who has practically lived in the Palace since the King's illness was a guest. During the day the Queen and her sons and daughter paid a brief visit to the sickroom to see the King.—*Reuter*.

OLUṢANIN.

---

Eleko Case, on or about the 3rd January, 1929.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby Price per bottle 3/3d & 2/3d

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.

Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

- Glaxo (large and small sizes)
- Vitafer—Brain Tonic
- Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
- Pile Pills 1/6
- Vibrona Wine 7/6
- Lactogen
- Kalzana
- Effective Pile Remedy 7/6
- Back and Kidney Pills 2/-
- Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos.
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
109, Griffith Street, Idumagbo? ... Malta

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣę ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Moue, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes; these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undertaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

——:o:——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orișirișị ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorișirișị ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.